# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 92. SATURDAY, APRIL 12, 1924. Fourpence.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

14 APR. 1924

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWỌN ẸGBẸ.

14 APR 1924

No. 7, Ita Ibode lailai, l'eti *Glover Memorial Hall*, (*Customs Street*,) EKO.






Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ransẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun rikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun ẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## M. D. MARTINS

23, SCALE SQUARE, LAGOS.

Ọgbẹni yi jẹ ẹniti o nşe ọti orişirişi. Ginger Ale, Şile mẹta abọ (3/6) fun Doz. kan ninu Igo Beer, ati Şile mẹta (3/-) fun ẹniti o ba fẹ ra pupọ bi Dozen marun (5 Doz) ati ju bẹ lọ.

Lemonade bakanna, Cider Champagne bakanna Soder Water ninu Igo kanna Şile kan ati Nain (1/9)

O npọn ọti ni Jebba Street, Ebute Mẹta.

Cable Address:— "Steinafrik" HAMBURG.

## E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neurwall 16/18, Hildebrandhaus.

*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for

English and Continental Goods

and

PRODUCE

Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**

*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

## ẸNIKEJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

# ERO YA WA RA.

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun-ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, A[illegible]ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

OWO ỌJA RẸ FANIMỌRA.

Ẹ LỌ RA TIYIN NIBẸ.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

ẸFUN TABI EDI ?

Ariwo sọ lala ni Alakoro ni Satide ọsẹ to kọja, nigbati ọdọmọkọnrin jọgọlọ kan ti a npe ni Sam—iṣẹ aranṣọ lo nṣe—fi ọbẹ pa ara rẹ, nipa fifi ọbẹ-ifari yun ara rẹ lọrun bi ẹran ; orişirişi ọrọ la gbọ nipa ohun ti a sọ pe o bi ọmọkọnrin na ninu ki o to dumbu ara rẹ bayi, apakan ni aya rẹ lo fẹ kọ silẹ nigbati iyẹn sọ fun pe ki o ka'lọ si oko fun itọju ara rẹ, ṣugbọn ti ọmọkọnrin na kọ pe on ko le lọ fi aşiri on han aná ; apakan ni ibanujẹ ohun abami to ṣakiyesi lara rẹ niti pe ko tun le gbe aya rẹ li ẹrẹkẹ jo mọ lo mu ki o ṣe bẹ ; apakan ni aya rẹ to bimọ fun na bu ni ebu ara ṣinşin to gbija ninu ọkọnrin na ; apakan si tun ni ironu airi'ṣẹ ṣe ati aya rẹ to fẹ kọ ọ silẹ lo mu ṣe bẹ ; bayi ni awọn enia nbu ti nwọn nla : nigbati awọn Ọpa Ọba wa gbe oku rẹ, agbara ẹjẹ ti nwọn la, ki nwọn to kọja ninu yara ti ọkọnrin na f'eṣu ṣe ara rẹ ko ni sisọ ; nigbati a *Jury* oku rẹ ni a wa ri ọbẹ ifari ti o fi ṣe ọṣẹ yi ni ọna-ọfun rẹ. Ẹjọ na şi wa ni Kotu Ọlọpa nisinsinyi.

Ẹniti a mọ faufau ni ọkọnrin yi o si ni iteriba fun ẹnikẹni lọpọlọpọ ; ti a ba ki "Ọga Agba Ọga Agba" ni ma saba npe wa, iṣẹ *Tailor* ti o nṣe si da loju. Ṣugbọn ohun ti o mu lẹburubu lati ṣe iru iṣẹ bayi fun ara rẹ, oju Oluwa nikan lo to ; nigbati a *Jury* rẹ tan, a gbọ pe awọn Ẹlẹwọn lo gbe oku rẹ lọ si itẹ. O ṣe ! ọmọ onibi-niran di oku Ọba nigbẹhin ọjọ rẹ. A ! imọran wo lo ju eyi lọ :—Ẹ

maṣe jẹki orun ki o wọ s'ori ibinu nyin, ẹ ma si ṣe fi aiye silẹ fun eṣu.

Baba t'emi d'ọwọ rẹ Baba ! ! !

OJOJO NṢ'OGUN ARA OGUN KO LE.

O fẹ diẹ si Balẹ Ilu Ọgbẹni Henry Carr I.S.O. ninu ọsẹ to kọja ; a tanma pe aisan na ti di fifuyẹ nisinsinyi.

ỌLẸ DARUN, B'ONILE NI'LE.

Girigiri ẹsẹ ti a gbọ ni apa Isalẹ Agbẹdọ ni Satide to kọja, mu ki a bere pe kilode ? T'ohun t'ẹnu bẹnı a ri ti awọn kan nti ọdọmọkọnrin kan lọrun gọgọ lọ si Ṣabu Ọlọpa, a sọ pe ọmọkọnrin yi fi ipa hu ọmọdebinrin kekere kan ni iwa iwọsi, tobẹ ti o di ogun ẹjẹ-yọyọ, a gbọ pe bayi ni ọdọmọkọnrin yi nṣe awọn ọmọdebinrin kekeke to nkiri ọja, lalai ni iṣẹ kan lapa ; Ọdẹlẹsinrin na şi "d'ẹru" Ọba nisinsinyi.

AGBAKO ORI EDE !

Ihin kan ni lati *Warri* pe Oyinbo Atukọ kan ara Jamani, ti o nşişẹ ninu ọkọ *Lavinda* ti ọdọmọdekọnrin kan ti a npe ni Samuel Ẹbun Cole s'omi tobẹ ti iyẹn fi ku. A o ṣe Kotu pataki (*Special Assize*) fun ati ba Oyinbo na ro'jọ nibi pe enia ti ọwọ rẹ ku.

OYINBO AF'AILOWO RA SEFU (*SAFE*) O JỌ NPE O MA KO GARI DA SI.

Ọwọ Ọba tẹ awọn Oyinbo ti a npe ni Drew ati King, ti nwọn ti gba ọgọrọ owo lọwọ awọn enia wa l'Eko nibi ni Ibadan ati ni Oṣogbo fun ǹwǹ ti nwọn ni nwọn nba awọn ara wa na ṣe.

Ile Parati, Olori-ọlọpa ni nwọn haya leti Itọ Oku Igboro ; o si ti niye ọpọlọpọ awọn enia ti awọn Oyinbo wọnyi ti de mọ'lẹ ; nigbakan nwọn gba ọgọrun pọun (£100) lọwọ

Ọgbẹni kan ti a npe ni Abudu Fọlami ti o ngbe apa Ile-ẹrọ Tika-Tore nibi, nwọn ni nwọn yio gba si'ṣẹ nigbati Ọgbẹni yi si reti iṣẹ na titi ti eti re Kotu lo la wọn ni'ja, ki Ọgbẹni yi to jaja ri owo rẹ gba nipa tita "Mọto" Alaru wọn lẹhin igbati o ti jare wọn tan. Bayi ni nwọn ṣupa ti nwọn ṣubi titi ọwọ Ofin fi tẹ wọn, ti a si wa wọn lọ; o ku ẹnikan ninu nwọn ki ọwọ tun tẹ, orukọ rẹ njẹ Offord.

A fẹ ki awọn enia wa ma kiyesara irufẹ awọn Oyinbo titun ti nwọn ni nwọn nmu ọwọ wa sarin wa nibi, laiye isinsinyi, nitoripe pupọ ninu wọnn dabi Ọni A-mu-ni-ma-da: nwọn ko ni ọkan lọwọ bi Aja, nṣe ni nwọn ngba owo lọwọ Aṣa pẹlu Awodi.

Bẹ si ni awọn Oyinbo wọnyi tun fa Ọgbẹni kan ti o njẹ Lemọmu lori nigbakan nipa gbigba ọgọrun pọun (£100) lọwọ rẹ fun ati gba si'ṣẹ.

A gbọ pe gẹrẹ ti ọmọdekọnrin na ti gba ipin ogun rẹ kan ti o jẹ Adọjọ pọun (£150) lo fa Ọgọrun pọun (£100) yọ ninu owo na fara to lọ gbe fun awọn Oyinbo yi ni ṣa-ndi, ṣugbọn a-lọ owo lo ri, ko ri a-bọ rẹ mọ Orukọ "Ile Ọwọ" awọn Jagun yi ko mọ niwọn, Ẹ kã wo:— *The Anglo-Scandinavian Trading Company;* loju wa, o dabi nwọn ni awọn njẹ "Ẹgbẹ Onisowo Ilu Majaku"—"Ara-ilewa" ki sã bimọ si tosi!!! (owe ni o) ṣugbọn a sọ pe nwọn ti f'ẹhin silẹ nisinsinyi nigbati ilẹ mọ wọn!

BALẸ ILU NPALẸ AJO MỌ, ORIṢA MA PE A T'ẸNU MI GBỌ.

A gbọ pe Ọgbẹni Henry Carr I.S.O. Balẹ Ilu yio lọ si Ilu Oyinbo ni ọjọ 25 oṣu yi. Ẹ ku ipamọ o!

IYA RE 'LE O, ILE LO LỌ KO ṢINA.

A ba awọn ọmọ ati ẹbi Mrs. Tom Jones (Ellen Tọwọbọla Jones) daro iku iya wọn to ṣẹlẹ ni'le rẹ, lẹhin-Ọgba ni *Wednesday* ọsẹ yi.

OYE YI RO TOTO.

Awọn Janma fi Alagba Kasumu Gbaja-bi-amila ti Olowogbowo joye Baṣọrun dipo Ọgbẹni Sanni Onigbanjo to ti joye na ri, ṣugbọn to tẹrigbaṣọ losẹ tokọja.

FIFẸ LO NFẸ IYAWO DI TABA!!!

Ọgbẹni C. J. Martins ti ibi-iṣẹ Gbagi-mọ'lẹ t'Ọba, yio gbe Omidan Lucretia Abẹkẹ Davies ti No. 38, Ita Taiwo Olowo, niyawo ni Ṣọṣi Onidunkun-Oyinbo ninu oṣu to mbọ. Ki Baba m' ọjọ ro!

ỌMỌ OLOWO AKE, A GBA FUN NYIN O!

Ni ọsẹ yi Olori Akọwe Ganran, Ọgbẹni J. H. Stanley Robbin, Ọmọ olowo Ake ka-Iwe-Aṣẹ ti Gomina ti fọwọsi lati sọ Igba-keji Adajọ Agba Sir Vander Meulen di Adele Adajọ-Agba lẹhin isimi oṣu diẹ ti Adajọ Agba pãpã Sir Ralph Combe gba, ẹniti o lọ si 'le ni lọlọyi. Eyi wun wa o.

---

IWA ITANJẸ KO YẸ BỌKINI.

Arakunrin wa kan Ọgbẹni Hamzat A. Mọgaji, ti Shakiti Street, Lagos, sin aburo rẹ Nimọta ni Iyawo ni *Sunday* ijọ 23rd oṣu March 1924. O pe diẹ ninu awọn ọdọmọkunrin Eko ti nṣe ati eyiti ki nṣe Ahmadia lati wa ba on ṣe ariya lori tabili ni irọlẹ ọjọ na, gbogbo nwọn si ṣe ileri pe awọn yio wa.

A ko le sọ gẹgẹ bi ẹgbọn iyawo yi ti na owo to fun ipese onjẹ silẹ fun awọn Bọkini yi, ṣugbọn o jẹ ohun ti o dun ni pupọ lati ri pe ko si ẹniti o wa ninu apakan ijọ awọn Ahmadia ti o npe ni Debating Club, bikoṣe mẹrin pere ninu ogunlọgọ enia pẹlu awọn diẹ ninu awọn ti ko si ninu ijọ ti Ahmadia. Iyoku di 'regbe, ọpọlọpọ onjẹ lo ṣ' ofò l' ọjọ na nitori enia ko pọ to.

A dupẹ pupọ lọwọ Ọgbẹni Alimi Afini ẹniti o ṣe Alaga ti o si gbiyanju pupọ lati da ẹgbọn iyawo na lara ya nigbati o ri ibanujẹ rẹ, nipa tito ti o to awọn enia diẹ to wa na ti nwọn si nfi ṣibi ati agunjẹ dara lori tabili bi Oyinbo, tobẹ ti inu rẹ ti o ti kun fun ibanujẹ yi si ayọ.

A dupẹ lọwọ awọn Ọgbẹni Rabiyu Giwa Badamọsi, olori agbawo ati Abasi A. Balogun fun wahala wọn ni Alẹ ọjọ na, Ọlọrun ko da ọmọ si o.

A ko le sọ bi ọpọlọpọ ti jẹun yo to, ti inu fẹrẹ ya fun ọpọlọpọ adin-dun, sibẹsibẹ alai ko wa awọn janma rẹ ko fun ni ayọ na gẹgẹ bi o ti yẹ k' o ri.

Eyi jẹ iwa ti ko tọ, ti ko si yẹ larin Bokini l' ọmọde l' agba, bi a ko ba si pa iwa yi da nigbagbogbo ni ọpọlọpọ enia yio fi owo ṣ' ofo lori onjẹ nitori iwa itanjẹ bayi, o si ya ni lẹnu pupọ lati ri irufẹ iwa bayi larin awọn ọdọmọkunrin Bọkini yi.

Ṣugbọn a gbọ pe igbeyawo pọ pupọ larin Janma wọn ni ijọ na, sibẹsibẹ nwọn ni lati jẹwọ tabi ranṣẹ pe idiwọ pataki yio wa fun wọn, nitori bi ina ba jo ni ati ọmọ ẹni ti ara ẹni ni a o kọkọ gbọn danu.

Bẹni lakoko ti arakunrin wa, Ọgbẹni Yusuf Adu, ti Okepopo fi nko ọmọ rẹ jade ti o pe Saraki Janma ti Ahmadia ni alẹ ijọ na, bayi na ni nwọn ṣe fun, ti o jẹ pe ọpọlọpọ wahala rẹ bọ si asan. Bi ko ba ṣe ọrẹ rẹ ti a npe ni Abdul Liamid Adams ẹniti o ti ṣokoto rẹ bọ idi ti o yọ ṣibi ti o pin gbogbo onjẹ na fun awọn aladugbo nigbati o di agogo mọkọnla oru ijọ na.

A bẹ awọn Janma yi ki nwọn ma ṣe jẹ ki okun Ifẹ ti o wa larin wọn tu, ki nwọn ma si ṣe ārẹ rara. Nitorina igi ti a ma tori rẹ gb' odi a ṣuna ere fun ni ya. Abọ ọrọ to fun ọlọgbọn.

A ki awọn arakunrin wa Ọgbẹni Kazal D. Oshodi ati Abdul K. Dawodu, nwọn ku inawo iyawo ti ọjọ ọsẹ *23rd March, 1924*, Ọlọrun ko fi adun si o.

A ko le sọ bi o ti yẹ wọn to nigbati nwọn nlọ mu iyawo ni iwọn agogo mẹfa irolẹ ti ojulowo Mọto oniyebiye ntowọ le ara won lẹhin ni opopo Ẹhin Ọgba (*Victoria Road*) bi ọjọ t' ọba gba 'de to bẹ gẹ ti oruku fi nta ku u ti ọpọlọpọ enia fi nkan sara si wọn.

Ọlọrun ko jẹ ki iru rẹ kari gbogbo wa o.

IYANDA.

---

### CHRIST'S DEATH WARRANT

"A DOCUMENT which archælogists believe to be the Roman military order under which Jesus Christ was tried has just been discovered by the French Government's ethnological mission in Southern Tunisia, ' says the *Sunday Express*.

"Christ was executed, it appears from this document, because He was called 'King of the Jews'—a claim that implied disloyalty towards Cæsar. The document is worded as follows :—

"'*To all Colonial Governors of the Roman Empire in Palestine and Near and Further Arabia :*

"'*Prophets and religious revolutionists have arisen among the people. These prophets are not to be interfered with under Roman law except when their teachings are of such nature as to cause disturbances among the people. In such cases they are to be effectively suppressed.*

"'*It is particularly desirable that these prophets be not allowed to interfere with the collection of taxes or with any other political affairs.*'

"The edict was signed by Augustus Cæsar."

*Public Opinion 14/3/24.*


ILE-ÒWÒ OYINBO ALALUMỌGAJI.

# John Holt

NI ỌJA WỌNYI FUN TITA

Sarotu "Alasia"

Kẹkẹ-ologere ( Elerin )

Kẹkẹ-Ologere ( *Rudge Whit-Worth* )

Panu Iborule

Awo

Awo-abọmafọ

Ẹja-abọmafọ

Iyẹfun

Sulfuri

Ẹfun

Alum

Ọda-dudu

Oriṣiriṣi Ọda-ikunle

Iṣo

Panu-kikọ'le

Iṣana ( Atukọ )

Ẹ bere ni Ṣabu **JOHN HOLT** ni Opopo-nla, ni **Eko.**

"*Ebani*" ni ede-waya ti ẹnikẹni le tọ si wọn nibikibi ni Eko tabi ni Ilu miran ni *Nigeria*.

## EKO AKETE.

Eko, Saturday, April 12, 1924.

### EKE L'ỌMỌ ARAIYE ẸNU WỌN L'ỌFA, ẸNU WỌN L'OJE!

Jake-jado gbogbo ibiti awọn Onigbagbọ wa lode aiye ni a mọ ọjọ ọla si Ọsẹ Ọpẹ, ninu eyiti Olukọ to bori Olukọ, ani Kristi gun Kẹtẹkẹtẹ lọ si Jerusalẹmu pẹlu ariwo nla, ti gbogbo ilu na si gbojikan fun igbe "Hosannah fun ọmọ Dafidi, Hosannah l'oke ọrun" !! t'ọmọde t'agba nduna lati fi ọla fun ẹniti ọla nṣe tirẹ, nipa titẹ aṣọ wọn soju ọna fun Kristi lati kọja l'ori rẹ awọn ti kc ni aṣọ ge ẹka-igi fun titẹ sọna bakanna, awọn to si ja imọ dani ko niye. Ẹ jẹ ki a duro bi ara wa lere gbolohun ọrọ meji tabi mẹta.

(1) Ẹkini ti awọn enia na ma kọ ri Kristi niyi, ẹniti o ti wa larin wọn fun ọjọ gbọrọ? Agbẹdọ!

(2) Kiloha mu irọkẹkẹ yi wa?

Esi ekini leyi:—Lati igbati Ọga nla yi ti nkọ awọn enia, ti o si ti nwasu fun wọn ni gbogbo igberiko Jerusalẹmu titi fi de Ilẹ Judea, ko ti fi igbakan jade bi Ọba si awọn enia ri, ti yio dogun pe nwọn nke rara niwaju rẹ, ti ilu si mi titi tobẹ ti awọn ẹlomiran fi mbere pe—Tani yi?

Esi Ekeji:—Nigbari awọn enia ri Kristi lọna yi lojiji, nwọn ro pe Ọjọ Bíbọ́ wọn "loko ẹru" Ijọba *Rome* lo nku si dẹdẹ: ṣugbọn aṣiro l'eyi. Jesu Aṣaju papa ko ha ti sọ lẹkan nigbati awọn A-ba-ni-w'ọran b'a-rida kan nbere ọrọ lọwọ rẹ, pe "Ijọba mi ki ṣe ti aiye yi"? Gigun to gun Ibakasiẹ wọ Jerusalẹmu ni àyá Ọla, jẹ ifihan pe nitotọ bi Olukọni O ti nkakiri gbogbo ilu, lati kọ ẹnikẹni ni Ọrọ Ọlọrun ati lati wasu pẹlu. Ṣugbọn bi o ti ṣe wọ Jerusalẹmu bayi ni'jọ na jẹri si aṣepari iṣẹ rẹ, eyiti o mu ki ayọ kun ọkan gbogbo enia ti nwọn fi nfo fẹrẹ, bi a-f'egbo-ludo: ṣugbọn kilatun ri? Ko lọjọ ko loṣu ki awọn enia wọnyi tun pa ilu wọn dà si "Mu kuro, Mu kuro, kan a mọ Agbelebu, kan a mọ Agbelebu!" Ẹnyin ara, bi aiye ti ri niyẹn, eyi si jẹ ẹkọ nla-nla fun gbogbo wa pe bi o ba ṣe gbẹdẹ fun ẹnikan diẹ a o ri ọgọrọ awọn ti o ma pe ara wọn ni ọrẹ oluwarẹ lọdọ rẹ, awọn ọrẹ A-ri're-ba-ni-jẹ-agbọn-isalẹ bi o ku larọ a ya lalẹ. Ṣugbọn jẹ ki ọ̀sà d'odi diẹ kinun fun irufẹ ẹnibẹ na ipakọ ni pupọ ninu awọn ọrẹ wọnyi yio kọ si. (A ko ṣaimọ pe awọn ọrẹ ati ojulumọ ojulowo-agbọrandun bi Iya ko si wa l'eni tere eji tere) bẹ ha kọ leyi nipati Kristi nigbati awọn *Jew* lọ sun ni ẹsun eke lọdọ awọn Alaṣẹ Ilu, pe o nṣẹ bi Ọba lati rọpo Kesari, awọn ti nwọn ti nyò-bó rẹ, ko ha di ọta rẹ ọsangangan bi?

Ẹkọ ribiribi ti a o ri kọ ni Iwasu Ọla yio jẹ Ẹkọ Ma-gb'ara-le-wọn, ati Ẹkọ B'Ọlọrun duro. Ninu gbogbo ofĩ, ọlã ti a le ṣalaba-pade ninu aiye yi, Olodumare nikanṣoṣo ni Baba Ab'ọwọ gbọgbọrọ ti nyọ ọmọ Rẹ l'ọ̀fin, yọ mi! yio si yọ wa ninu gbogbo Ọfin Aiye. *Amin.*

## NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF
**LONGE ADELAKUN**
(Deceased)

*Pursuant to the Statute 22nd and 23rd Victoria Chapter 35 intituled "An Act to further amend the law of property and to relieve Trustees*

Notice is hereby given that all Creditors and other persons having any debts claims or demands upon or against the estate of LONGE ADELAKUN late of 9, Strachan Lane Lafiaji in the Town of Lagos in the Colony of Nigeria who died in Lagos aforesaid on the 27th day of June 1923 intestate and administration of whose personal estate and effects was granted to KADIRI AYENI ADELAKUN of 9, Strachan Lane, Lafiaji, Lagos aforesaid by the Supreme Court of Nigeria on the 24th day of March 1924, are hereby required to send in particulars in writing of their debts claims or demands to me the undersigned Solicitor to the Administrator at my Office at 4, Oil Mill Street in Lagos aforesaid on or before the 31st day of May 1924 and Notice is hereby further given that at the expiration of which time the Administrator will proceed to pay and distribute the assets of the said deceased amongst the persons entitled thereto having regards only to the claims and demands of which the said Administrator shall then have had notice and the said Administrator will not be liable for the assets of the said deceased or any part thereof so distributed to any person or persons of whose claim or demand he shall the not have had notice.

And all persons indebted to the said estate are hereby required to make immediate payment of their indebtedness.

Dated this 10th day of April, 1924.

S. H. A. BAPTIST,
*Solicitor to the Administrator.*

## DOKITA JOHN RANDLE.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f' oji,

Gẹgẹ bi ọpọlọpọ wa ti mọ, ẹniti a da orukọ rẹ soke Wosika yi jẹ ọkan ninu awọn enia pataki ni ilẹ yi, on si ni Baba-ẹgbẹ "PEOPLE'S UNION" ti nwọn nṣe ni Ilupesi.

Nwọn da ẹgbẹ yi silẹ li akoko Owo-omi (*Water Rate Agitation,*) awọn Onifila-funfun, Erelu, Aṣọ-bọn ati enia pataki-pataki miran ni Kiriyo ati Imale li o si wa ninu ẹgbẹ na nigbana. Li akoko yi, iran dun 'wo ni Ilupesi, pāpa li ori Agbá-epo ti o wa nibẹ nigbana.

Owo ti ilu da si ẹgbẹ yi ko kere, ṣugbọn asinwa, asinbọ, a nsan Owo-omi loni, pẹlu gbogbo ihalẹ Baba-ẹgbẹ na, ki Ọga awọn Gomina, (*Secretary of State,*) to tẹ Waya ikilọ wipe, bi on ba tun gburo nipa ọrọ Owo-omi, orò yio gbe e.

Nitori eyi, ati pataki nitori iṣesi awọn Alakoso ẹgbẹ na ti ko wọ fun awọn Oloye ati enia pataki miran nibẹ mọ, nwọn fi ẹgbẹ silẹ. Fun iwọn ọdun mẹtala lẹhin na, ẹnikẹni ko si gbọ ohunkohun nipa ẹgbẹ na mọ; yala o kú ni, tabi o yè ni, titi di iwọn ọdun kẹta ọhun, nigbati a ri aworan (*Photograph*) Dokita Randle ninu Iwe-irohin kan ni ilu Oyinbo ti a npe ni "*West Africa,*" pẹlu ọrọ ti o sọ nibẹ nipa Eko, pāpa nipa ẹgbẹ "People's Union."

A ko le ṣẹṣẹ sọ wipe gbogbo ọrọ Ọgbẹni yi nibẹ nipa Eleko dara tabi ko dara, nitori isọkusọ na ko fi ara sin—o buaya, o de gongo.

Ṣugbọn nigbati Dokita Randle pada de ilẹ yi, lẹhin ti o yà ni Saro, (Sierra Leone) tan, eti on ipa gbọ ponpon ọrọ ninu iwe kan ti Ọgbẹni Herbert Macauley ṣe, iwe ti okiki rẹ si pọ tobẹ gẹ Gomina, Ọlọla Hugh Clifford ko tiju ati sọ ọ ni gbangba wipe on ya ọkan ka ninu rẹ.

Titi di oni, Dokita Randle koi ti f'esi Iwe na: kaka bẹ, ni apejẹ (*Dinner*) ti awọn mejila kan ti o pe ara wọn ni "Reform Club" ṣe ni Gand Hotel fun awọn Bọkini Oyinbo meji kan lẹhin ti Iwe Makọli ti jade tan, nibẹ ni o nfi atamọ-mọ-atamọ nipa esi akoni ti Ọgbẹni Tommy Jackson fun Gomina, Sir Hugh Clifford ninu Iwe-irohin rẹ, "*The Lagos Weekly Record,*" nitori ọrọ alufanṣa ti Gomina sọ si Iwe-ẹbẹ ti ilu fi ṣọwọ si i, nipa ọrọ Eleko ti awọn alamọkan ati opè miran ro wipe ko ni atunṣe mọ, ti awa si mọ wipe ọmọde li o nṣe irufẹ enia bẹ, ati wipe ọwọ baba ni nwọn nwo, nwọn ko wo ẹsẹ baba.

Li ẹhin ti Dokita Randle ti sọrọ bayi tan nipa Iwe-irohin Ọgbẹni Tommy Jackson, ni Gomina pāpa dide, o si gbe ẹnu le Iwe ti Makọli ṣe nipa Dokita yi, ẹniti Gomina pe ni olõre Makọli. Yala Dokita Randle pāpa li o pe ara rẹ ni olõre Makọli fun Gomina ni o, tabi Gomina li o kan ro bẹ fun ara rẹ ni o, awa ko mọ; ẹnikẹni ninu awọn mejeji ko sọ irufẹ õre wo ni Dokita Randle ṣe fun Makọli, awa si mọ wipe fuja-ete lasan ni, gẹgẹ bi ẹnyin pāpa ti ri i ka ninu Iwe-irohin "*Lagos Weekly Record*" li akoko na.

Ko pẹ lẹhin eyi, ni asiko ati yan enia mẹta si Igbimọ Aṣẹ'lu (*Legislative Council*) de, awọn ẹgbẹ "People's Union" si ṣe ipade kan ni ile Afariogun (*Glover Memorial Hall*) Dokita Randle ni alakoso Ipade na, enia mẹtadi-logọrun (97) pere li o si wa nibẹ; pupọ ninu wọn ko si nṣe ọmọ-ẹgbẹ na rara. Ọdọmọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ A. B. Laotan to ra ni ẹgbẹrun ọkẹ ni ọjọ na, nigbati o nfi paṣan ọrọ nọ awọn alakoso Ipade na. Iyoku di iregbe, nwọn fẹrẹ ta iporogan ki Ipade na to tuka: gbogbo Ipade ẹgbẹ yi lẹhin na ni Ilupesi ni nwọn nṣe, nwọn koi si ti to yọju si Glover Hall bi ẹgbẹ Tun'luṣe, (*The Nigerian Democratic Party*).

Enia mẹta, Oyinbo kan, Enia Dudu meji ti awọn ọmọ ẹgbẹ Dokita Randle yi di'bo fun li o bo'lẹ pirapira li ọjọ idibo. Enia mẹtẹta ti Democratic Party li o pegede.

Gẹgẹ bi a ti sọ ṣiwaju, nigbati Dokita Randle mbọ lati Ilu Oyinbo, o duro diẹ ni Saro, a si gbọ wipe nibẹ li o ra ilẹ kekere kan, ti o fi kọ Ṣukuru (*Anglican Day School*), eyiti nwọn ṣí ni lọlọ yi, ti ọmọ Saro diẹ si nkọ ẹkọ nibẹ. Nipa ṣiṣe bayi, Dokita Randle ṣe õre ti o nisan diẹ fun awọn ti o ka si ara ilu rẹ, a si ni lati dupẹ lọwọ rẹ fun eyi. Ṣugbọn Saro ha ni ilu Dokita Randle nitotọ?

Ti a ba yọ ọwọ diẹ ninu awọn ara igberiko Saro kuro, ko da ni loju wipe Saro atata kan tun kù ti ko nṣe wipe a mu baba nla tabi iya nla rẹ ni ẹrú, ti a si di wọn ni igbekun lọ si ibẹ lati ilẹ Yoruba.

Bi a tilẹ bi Dokita Randle si *Sugar Loaf Mountain* ni Saro, Yoruba fáufau ni Baba rẹ; ti mo ba si ranti daradara, Ojo-yẹugẹ, alagada-ogun ni orukọ abisọ Daddy na.

Njẹ bi eyi ba ri bẹ, ko ha yẹ ki Dokita Randle tete kọ ṣe õre pataki fun ilẹ Yoruba bi Eko ná, ki o to lọ ṣe nkan bẹ si Saro? Ki a tilẹ wipe ko ba Yoruba tan rara, sibẹsibẹ, ilẹ Yoruba ni Eko, ko nṣe ilu Saro. Ilẹ yi ni Dokita Randle ti ri iba ãsikí ati anfañi ti o njẹ ọlá rẹ loni: ilẹ yi li o gbe nṣe iṣẹ, ilẹ yi li o kọ ile si, a ko si le fẹ ọmọ Yoruba kù ninu awọn aya rẹ li akoko kan ri. Ilẹ yi gbè Dokita Randle pupọ, tabi-tabi ko si ninu eyini; bi a si ti dupẹ lọwọ rẹ, ti a si tọrọ ibukun Ọlọrun fun u nitori Ile-ẹkọ ti o kọ si Saro, bẹni a si tanına wipe yio fi si ero lati ṣe nkan ti o dara ju bẹ lọ fun Eko—iyẹn ti o ba ri afo rẹ.

**"It is more blessed to give than to receive."**

Emi ni tinyin nitõtọ,

ATARI-AJANAKU.

## BABA ONIJẸKUJẸ, AB'AJUFU L'OKE AIYA, PẸLẸPẸLẸ O.

Gbangba d'ẹkun kedere bẹ wo ni ọrọ ti a sọ sinu Iwe Irohin wa ti ọjọ 15 oṣu *March* to kọja, nipa "Ogun ẹtẹ" ti a sọ fun ni pe ọmkan ran ọmọde kan lọ da si ile ẹnikan ni odo Oluṣi; iwa-onijẹkujẹ baba ọmọbinrin kan lo mu esekoyi ana wa fun iya ọmọ na, ti o fi huwa agba ki wa lọja k'ori ọmọ titun ki o wọ, kiṣe ogun ẹtẹ ni ogun na. A o sọrọ yi ni kikun l'ọsẹ to mbọ, lati fi iwa ibaje ti awọn baba miran ni han lati sọ ọmọ wọn di o-ni-gba-egbere nipa fifi wọn jẹ owo lọwọ orisirisi ọkọ.

---

**STOP PRESS!!!**

It is understood that the following Ladies :—

Mrs. Angelina Beecroft, Miss Morrison and Mrs. Gomez, were engaged by the Government as Women Apprentice—Book Binders during the week.

Really, we are getting on!

---

## Notice of Removal.

Barrister O. Jibowu removed from No. 55, Broad Street, to 58, Palm Church Street, Lagos.

---


## AGA, AGA, AGA.

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.

OWO PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI, (1½D.) KỌBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ ALABOJUTO,

Ọgbẹni J. A. OSHODI,

No. 26, ITA ỌBUN-EKO,

LI EKO.



PAGIDARI! ONIṢEGUN TITUN NIYI.

Ẹ ha ti ri *Native Doctor* S. Bankọle Abẹruagba Mafarapa ri? Bere rẹ ni 23, Pedro Street, Oko Awo, ati ni 1, Forsythe Street, Lafiaji. Wa fun gbogbo arunkarun ti o ba mba ọ ja a o si sọ dię fun ọ.

| | |
|---|---|
| *Epilepsye*—Warapa | *Madness*—Were |
| *Small Pox*—Ṣọnpọnọ | *Leprosy*—Ẹtẹ |
| *Ulcer*—Egbo | *Rheumatism*—Lakuregbe |
| *Bronchitis*—Ikọ aiperi | *Elephantiasis*—Jakutẹ |

*Dysentery*—Igbẹ ẹjẹ, Ọrin
*Dermatitis*—Ekuru, Ifan
*Malaria Fever*—Arun Iba
*Pneumonia*—Igbonọ, Ikọ.

Bi obinrin rẹ ko ba tete ni oyun, mu wa.

Bi obinrin rẹ ba ni oyun ki o le bi pẹlu irọrun mu wa.

Bi obinrin rẹ ba nbi abiku mu wa.

Bi aran ba mba obinrin rẹ ja mu wa.

Bi aisan amodi ba mba ẹnikẹni ja ki o wa.

Bi obinrin rẹ ko ba ri nkan oṣu rẹ, mu wa.

Bi Ẹda ba mba obinrin rẹ ja, mu wa.

Bi arun aṣiri ba mba iwọ papa ja wa.


---

## IN MEMORIAM.

In loving and affectionate remembranc of my dearly beloved friend

MANUEL DEALTRY BARBOZAR,

Whose sun went down on the 9th April, 1923.

"Though short thy life, not short as Heaven reckons,
There, not as here, they measure life by love,
And when the Master home His servant beckons,
Full the reward awaiting each above."

*Requies cat in pace.*

A. AKINDELE DA MATHA SANT' ANNA,
(*Ojo nrọ si koto*).

Ifẹmọ̀le o ku Chambers,
59, Lawson Street,
Lagos, Nigeria.
9th April, 1924.

# ỌRE

Ẹ LỌ RA NKAN EASTER NYIN NI ṢABU

# R. LOMAS & CO.

80 & 192, BROAD STREET.









Nwọn ṣẹṣẹ ni orişirişi ọja ni tita fun awọn Ajiṣafẹ ati awọn Ọmọge ni ọpọku ọyọku, awọn bi Aṣọ ati Ibọsẹ Ṣẹda, Bata-totilẹ, awọn Aṣọ Yọmini, Akẹtẹ lorişirişi, Awọtẹlẹ, Collar Lekeleke, Ties ati awọn Ọja miran.

Ẹniti o ba gbọn, yio wa si Ṣabu wa mejeji na, a o si fi ọpọ Ọja to ti jire su u; bi ọ ba fẹ ohun kankan, ẹ sa bere rẹ; "b'o nfo ma ba ẹ lọ" ọja wa bi aba.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)
Masses Isin Arọ.
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.
(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.
ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church, | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Rev. C. A. Ṣonmi |
| 6.30 p.m. | do. | Mr. C. W. Wakeman |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. S. V. Latunde |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | do. | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. M. N. Q. Sagoe |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | Rev. S. A. Pearse |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. C. W. Faulkner Shaw |
| 7 p.m. | do | Bro. Adebiyi Tepowa |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | Rev. G. A. Oke |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | Bro. A. M. Williams |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | Rev. M. B. Newton |
| 6.30. p.m. | do. | Rev J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akinọla |
| 6.30 p.m. | do. | do |
| 6 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Ṣomuji. |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Rev. I. O. Oyekunle |
| 4.30 p.m. | do. | do. |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. A. T. O. |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. J. R. Williams |

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6 p.m. | | Bro. Joseph Bandele |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. F. Oshodi |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. | Respect'ble Bro. Arinọla Ọkọya |
| 7 p.m. | Prof. Adeoye Deniga. |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM.)**

| | |
|---|---|
| 6 a.m. | Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde |
| 5.30 p.m. | Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.) |

**ZION CONGREGATIONAL.**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Locum Tenens. |
| 4 p.m. | do. | do. |

**SALVATION ARMY.**

| | | |
|---|---|---|
| 10 a.m. | Glover Memorial Hall | Capt. A. A. da Costa. |
| 7 p.m. | do. | do. |

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrell

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

Bi awọn Oyinbo Oniṣowo ilẹ yi ti gba awọn Ọja wọnyi si l'ọsẹ yi ni eyi:—

EKURỌ

£13 10 0—£14 fun *ton* kan.

EPO.

£25—£27 fun *ton* kan.

COCOA.

£19—£21 fun *ton* kan.

---

## KANO.

ẸPA.

£12—£12 5 fun *ton* kọkan.

AWỌ (*Skins and Hides.*)

Skins 1/9d fun lb kọkan.

Hides 5d fun lb kọkan.




# ERVEN LUCAS BOLS

## AMSTERDAM

**1575**

---

Whenever you see the word Bols it means a reputation of over 300 years.

***ols very old LIQUEUR GIN is the Gin for the man of good taste.***

# STONE JARS AND GLASS JARS

## **5s.** per Bottle

***FROM***

# GRACE BROS.

***— DRINK IT NEAT. —***

# R. S. JAMESON,

**Licensed Auctioneer & Appraiser,**

Broad Street, LAGOS.

***Prompt, reliable and intelligent Service.***

Property real and personal sold and valuations made for Probate.

Low rates of Commission and immediate settlements.

## H. S. Freeman

(Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.)

Dealer in all kinds of Photographic Materials

**Films, Post Cards, Views etc.; etc, on hand.**

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed.

*Office* :—106, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

*Telegraphic address* :—" **FREEDE** " LAGOS.

P. O. Box 495.



### ILE OWO KADUNA

to mbẹ lẹgbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Thomas ni 75 ati 81, Ita Odunfa, ( Anikantamo ) L'Eko.

Awa ni orişirişi Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ pupu-pupu ni tita, a si ni awọn " Ero-ija " wọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 l' a ti wa lẹnu işẹ yi, awọn ọja wa si to ọja o ni igba pọun (£200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan tabi pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ma pe'ro: a si nra awọn "oku" Kẹkẹ-ologere, oni-pupu-pupu, ati Ẹrọ-akọrin (Gramophone) ti a ntun şe ti a si tun nta ...o pọ̃, bi £3, £4, £6 10 fun awọn ...ti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe şọwọ si Olotu Ile-owo —Ọgbẹni SAM ADE CLAY ni adugbo ta darukọ loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ ni gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.



### AIYELẸSỌ ỌLARINDE

Repairer of all kinds of Bicycles, Gramaphones, Fitting and Sewing Machines.

*Workshop* :—20, WILLIAMS STREET, LAGOS.

*Residence* :—135, IGBOSERE ROAD.

**Charges Moderate.**






*4/6 each.*

## The Kaduna Store,

75 & 81, ODUNFA STREET,

*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*

ẸBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to *buy* always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz :—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor :—

SAM ADE: CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS :—Cash with Orders.



### The Nigeria Commercial Training Institute.

ESTABLISHED JANUARY 1924.

The above Institute offers students an opportunity to undertake its Training in Short-hand, Typewriting and Civil Service English.

Further particulars can be obtained on application to :—

J. OLOYEDE DAVIES,
*Principal and Proprietor.*
10, Upper Offin Lane,
Lagos, Nigeria.

TERMS :—

Absolute satisfaction with results, or money refunded.

## A. KESSLER,

7, Labinjo Lane, Williams Street.
*P.O. Box 459.*
SAMPLE SHOW ROOM.
Samples of all wanted goods exhibited.
*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,
Hamburg, Germany.









**Sale of**

Hand and Foot Sewing Machines "Alder" and "Mundlos," Pilsener Beer, "Lion" Brand per case 31/-, Champagne per case 24/2, £3. 5. 0.

Earthenware, Carpets, Berlin Wool, Lamps, Clay Pipes, Kitchen Clocks, Euergon Medicine, Fez Caps, Cycles Lady's and Gent's, Stoves

*Orders for any kinds of goods find quickest execution.*

**For general information :**

A new lot of Sewing Machines has arrived with last Steamer. For Sale: I have further Records, Campbeds, Indescendant High Power Lamps at special cheap prices.

*A visit to my Show Room will give you satisfaction.*



## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*



## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi şe ile l oşo. A ni ti titę oku Jesu, ti igbati a da a li ęb iku, ti Onję-alę ikęhin. A ni ti Adam ati Efa, ti işędalę aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla rę, ati nigbati o di ęranko; ti obirin ti o fi ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọşę Olọwọ—agaga Iyọ-iyọ mbę lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o b fę ę ni *iponu* a le ta a fun o, Işana Alapoti fun tita ko si bi a ti nşe wọn. Orişirişi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa şowo ko ma jere tirę, nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fę ja ir wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn :—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ęhin ok kọwe şowọ yala ni ede Gęsi tabi ti Yoruba si :—

E. O. AMBĘ & BROS,
28, Moloney Bridge Street, Lag
(*Lęgbę awọn Onişowo A. J. Tangalaki*
Idumagbo, Eko.



## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orişirişi Egbogi lo şęşę de f wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbọ orişir, ogun Ęda, ogun arun aşiri, ogun Arẹmọ ogun Onigbameji, ogun Aran orişirişi, ogu Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mā to lęsęsę.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si ję l idan.

Ọrę, ę lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nib ti a gbe nta wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.